# Ipa Pàtàkì tí Orín ń Kó Nínú Ètò Ogun Jíjà Nílẹ̀ Yorùbá

**Ọ̀wọ́adé Sunday Caleb**
*Department of Linguistics, African and Asian Studies*
*University of Lagos, Akoka, Lagos State*
*sundayowoade91@yahoo.com*

***Àṣamọ̀***

*A kò lè ṣòdiwọ̀n ipa pàtàkì tí orín máa ń kó nínú ètò ogun jíjá láwùjọ ẹ̀dá káríayé, pàápàá jùlọ, láwùjọ Yorùbá. Yorùbá ní orin níí ṣaájú ọ̀tẹ̀, bí ọwọ́ gẹngẹ ṣe ń ṣíwájú ijó. Ó sì hàn pé ọ̀tẹ̀ níí dogun daáwọ̀, tíí fa yánpọnyánrin, sọ̀lú dahoro. Orin náà níí mú kóríyà bá àwọn ọmọ ogun lójú ogun. Ìdí nìyí tí a kò fi lè kóyán orin kéré nínú ètò ogun jíjà láwùjọ Yorùbá. Lára àwọn orin ọ̀hún ni orin òwe, ìmọ̀ràn, àṣamọ̀, ọ̀tẹ̀, ìfẹ̀hónúhàn, ìṣìpẹ̀, àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ. Ọ̀pọ̀ onímọ̀ lítíréṣọ̀ Yorùbá ló ti ṣiṣẹ́ lórí ewì alohùn nínú àṣà ilẹ̀ Yorùbá lọ́nà kan tàbí òmíràn. Wọ́n sì gbìyànjú láti ṣàfihàn ipa pàtàkì tí wọ́n ń kó nínú àṣà àwùjọ Yorùbá tí ọ̀kọ̀ọ̀kan wọn ti jẹyọ. Àmọ́, wọn kò fúnka mọ́ ipa pàtàkì tí orin ń kó nínú ètò ogun jíjá láwùjọ Yorùbá. Ẹ̀yí ló fà á tí pébà yìí fi ṣe àgbéyẹ̀wò ipa pàtàkì tí orin máa ń kó nígbà ogun jíjà ní àwùjọ Yorùbá. Tíọ́rì Ìfojú-ìmọ̀-ìbára-ẹni-gbé-pọ̀ ti lítíréṣọ̀ (Soṣíọ́lọ́jì lítíréṣọ̀) tí ó tọ́ka sí ìbáṣepọ̀ tó wà láàárín iṣẹ́-ọnà, oníṣẹ́ ọnà àti àwùjọ gẹ́gẹ́ bí ẹ̀ta-òkò ni a lò láti ṣe ìtúpalẹ̀ iṣẹ́ yìí. Ìwádìí yìí ṣàfihàn iṣẹ́ pàtàkì tí ọ̀kan nínú àwọn*

*ewì alohùn ń ṣe nínú ètò ogun jíjà ní àwùjọ Yorùbá, yálà ní pípẹ̀tù sáàwọ̀, ṣiṣe kóríyá fún áwọn ọmọ ogun, ríru- ọ̀tẹ̀ sókè, ìfẹ̀hónúhàn, gbígbani nímọ̀ràn, ìpàṣamọ̀ àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ. Ó hàn ní ìkádìí ìwádìí yìí pé àwọn ọ̀kọrin pẹ̀lú àwọn ará ìlú kò kàn máa pèdè ajẹmọ́-ogun lásìkò ogun láwùjọ Yorùbá lásán, bí kò ṣe pé láti jẹ́ kí omi àwùjọ tòrò, kí ó sì dùn-ún gbé fún tẹrú-tọmọ.*

**Kókó ọ̀rọ̀**: Orin, ewì alohùn, ogun jíjà, Soṣíọ́lọ́jì lítíréṣọ̀, àwùjọ Yorùbá.

## Ìfáárà

Bí ìgbìn fà, ìkarahun a tẹ̀lé e lọ̀rọ̀ orin àti ogun jíjà jẹ́ láwùjọ Yorùbá, àti láwùjọ ẹ̀yà gbogbo kárí-ayé. A sì tún lè sọ pé Gẹ̀gẹ̀ lẹ́yìn Apènà ni orín jẹ́ sí ogun jíjà nílẹ̀ Yorùbá. Bí a bá sọ pé orin laya, ọ̀tẹ̀ lọkọ, ogun sì jẹ́ ọmọ tí wọ́n bí, a ò jayò pa. Àwọn orin tí a ṣe àgbéyẹ̀wò wọn ni àwọn orin tí àwọn jagunjagun tàbí ará ìlú kọ nígbà àwọn ogun bí ogun Ìjàyè (1860-1865), ogun Ìpẹ́ru, ogun Gbánámú (1830), ogun Àdùbí (1914-1918) àti ogun Àgbẹ́kọ̀yà (1968-1970) àti àwọn orin mìíràn tí ó jẹ mọ́ àkórì iṣẹ́ yìí. A tún fi ọ̀rọ̀ wá àwọn àgbà tó nímọ̀ nípa àwọn ogun tó wáyé nílẹ̀ Yorùbá lẹ́nu wò**.** Níbi tí a tí rí àwọn orin ajẹmọ́ ogun gbà. Àwọn orin tí a rí gbà ní oko ìwádìí náà ní a sì gbé yẹ̀wò nínú iṣẹ́ yìí.

Àwọn Yorùbá fẹ́ràn orin púpọ̀ láwùjọ wọn. Ìdí nìyí tí kò fi sí ohun tí ó ń ṣẹlẹ̀ ní àwùjọ wọn tí wọn kò lè kọrin nípa rẹ̀. Ìran Yorùbá nífẹ̀ẹ́ láti máa fi orin gbé ohun tó jẹ wọ́n

lógún jáde, yálà èyí tó jẹ mọ́ ìdùnnú tàbí èyí tó jẹ mọ́ ìbànújẹ́ (Fájẹ́nyọ̀, 2016:157). Awólálú àti Dọ̀pámú (1979) nínú Ajíkòbi (2000:ix) sọ pé:

> In all, songs tell stories of the people's past…they also express the joy and sorrows of the people, their assurances, hopes and fears of the future and life after death.
>
> Ju gbogbo rẹ̀ lọ, orín máa ń ṣàfihàn ìtàn àwọn ènìyàn tó ti kọjá…wọ́n sì máa ń ṣàfihàn ayọ̀ àti ìbànújẹ́ àwọn ènìyàn náà, ìdánilójú wọn, ìrètí àti ẹ̀rù nípa ọjọ́-ọ̀la àti ayé lẹ́yìn ikú.

Bí ọ̀rọ̀ orin ṣe rí gẹ́lẹ́ láwùjọ Yorùbá ni àwọn onímọ̀ yìí sọ. Kódà, wọ́n jẹ́ kí á mọ ipa pàtàkì tí orin ń kó ní ìgbé ayé ẹ̀dá, pàápàá láyé àwọn ọmọ Yorùbá. Iṣẹ́ pàtàkì tí Awólálú àti Dọ̀pámú ní orin ń ṣe láwùjọ ẹ̀dá yìí bá ipa pàtàkì tí àwọn orin tí a kó jọ fún àgbéyẹ̀wò kó láyé àwùjọ Yorùbá tó kọ wọ́n nígbà ogun tí wọ́n ti kọ wọ́n. Lákọ̀ọ́kọ́, gbogbo àwọn orin tí a lò mú gbogbo ìṣẹ̀lẹ̀ tó bí wọn wá sí ìrántí àti etí-ìgbọ́ àwọn ọmọ Yorùbá. Yorùbá bọ̀, wọ́n ní 'bí ọmọ ò bá bá ìtàn, á bá àrọ́bá; àrọ́bá sì nìyí, baba ìtàn ni ó jẹ́'.

Agbájé nínú Fájẹ́nyọ̀ (2016:157-158) ní 'orin ní agbára ní ilẹ̀ Yorùbá débi pé ó lè múni ṣìwà hù tàbí kó yíni lọ́kàn padà sí rere'. Òtítọ́ ni èrò onímọ̀ yìí, ó sì jẹ́ àrídájú nítorí pé ó hàn nínú àwọn orin ajẹmógun tí a gbéyẹ̀wò pé ọ̀pọ̀lọpọ̀ ogun tó ṣẹlẹ̀ nílẹ̀ Yorùbá ló jẹ́ pé orin ọ̀tẹ̀ ló bí wọn, àti pé orin náà níí sábàá ń fòpin sí ogun tó máa ń wáyé

láwùjọ Yorùbá. Èyí túmọ̀ sí pé irinṣẹ́ kòṣeémánìí pàtàkì ni orin jẹ́ nínú ètò ogun-jíjà ní ilẹ̀ Yorùbá.

Ní tirẹ̀, Adébàjọ̀ (2016:247) jẹ́ kí á mọ ohun tí orin jẹ́, pàtàkì rẹ̀ àti ìwúlò rẹ̀ láwùjọ Yorùbá nígbà tí ó sọ pé:

> Ewì lorin, orin lewì. Kòṣeémánìí ló jẹ́ fún ìran àṣùwàdà. Ọ̀nà tó pàtàkì láti gbé èrò ọkàn wa jáde ni orin kíkọ. A fi ń wàásù, a fi ń kìlọ̀ ìwà, à ń kọrin láti fa ìjàngbọ̀n lẹ́sẹ̀, à ń fi orin tú ìbàjẹ́ ọkàn ká, à ń kọrin láti mú iṣẹ́ yá…

Adú àti Adéríbigbé (2016:402) ní 'orin dàbí ìlù olójú méjì, gẹ́gẹ́ bí ó ṣe wúlò fún ẹni tó ń kọ ọ́ náà ló ṣàǹfàní fún ẹni tó ń gbọ́ ọ́ nítorí a máa ń fi orin pàrokò'. A lè sọ pé orin jẹ́ okùn ẹ̀mí àwùjọkáwùjọ tí ẹ̀dá ènìyàn ń gbé.

Ipa pàtàkì ni ogun jíjà kó nínú ìtànkálẹ̀ ìran Yorùbá. Èyí ni kò jẹ́ kí ogun jíjà jẹ́ àjòjì sí àwọn ẹ̀yà Yorùbá láti àárọ̀ ọjọ́ wá. Àṣà ogun jíjà yìí ló tètè ṣàfihàn ẹ̀yà Yorùbá káríayé gẹ́gẹ́ bí ẹ̀yà àárọ̀ àti ẹ̀yà tó fẹ́ràn ogun jíjà. Yorùbá bọ̀, wọ́n ní: Ohun méjì làá bá rogun: èkíní, n ó mẹ́rú; èkejì, n ó pa ọ̀tá, ṣùgbọ́n bí a bá dé ojú ogun tán, ẹ̀kẹta a máa báni, wọn a sì mú olúwa rẹ̀ lẹ́rú. Òwe yìí fi ohun tí ogun jíjà jẹ́ láwùjọ hàn pé kò sí ẹni tó lè mọ òpin ogun jíjà láti ìbẹ̀rẹ̀. Lóòótọ́ ni pé kò sí jagunjagun tí yóó gbàdúrà pé kí ogun kó òun, àmọ́ ọ̀pọ̀ ìgbà ni igi tí ẹ̀dá bá fojú rénà máa ń gún un lójú, tí á sì tún ṣẹ́ mọ́ ọn lójú pẹ̀lú.

Ọ̀pọ̀lọpọ̀ àwọn onímọ̀ ló ti ṣiṣẹ́ lórí ogun jíjà láwùjọ ẹ̀dá, pàápàá láwùjọ Yorùbá. Wọn kò ṣàìsọ ohun tí ogun jíjà jẹ́, bí ogun ṣe máa ń ṣẹlẹ̀ àti bí ètò ogun jíjà ṣe máa ń wáyé.

Kódà, wọ́n yànnàná àwọn ohun tí ó máa ń fa ogun jíjà láàrin àwọn ìlú méjì tàbí jù bẹ́ẹ̀ lọ nílẹ̀ Yorùbá àti káríayé. Oríṣiríṣi ogun tí àwọn Yorùbá jà láwùjọ wọn àti ìgbà tí wọ́n jà wọ́n kò farasin nínú iṣẹ́ àwọn onímọ̀ náà. Lára àwọn onímọ̀ ọ̀hún ni Johnson (1921), Oyèrìndé (1934), Abraham (1958), Àjàyí àti Smith (1971), Adéoyè (2005) àti Oyèlàdé (2011). Nínú iṣẹ́ àwọn onímọ̀ wọ̀nyí, ó hàn pé ìṣètọpinpin ogun jíjà nílẹ̀ Yorùbá kò lè ṣeé ṣe láìfi ti ìtàn àti ti ìṣèlú àwùjọ Yorùbá mọ́ ọn. Èyí ló mú Awẹ́ (1975:267) sọ báyìí:

> Any attempt to understand the history of the Yorùbá must therefore include a detailed study of their warfare: for war is a manifestation of the break-down of normal political relationship.
>
> Ìgbìyànjúkígbìyànjú láti ní òye nípa ìtàn àwọn Yorùbá ní láti ṣe èkúnrẹ́rẹ́ àlàyé nípa ètò ogun jíjá wọn: nítorí pé ogun ní àbájáde ìdojúrú ètò ìṣèlù wọn.

Ní èrò ti Adéoyè (2005), méjì ni ogun tí ó lè kojú ẹ̀dá láyé. Ó ní àkọ́kọ́ ni ogun àdájà, tí èkejì sì jẹ́ ogun àjàkúakátá. Ogun àdájà ni ó pè ní àwọn wàhálà tí ó máa ń dojú kọ ẹnì kọ̀ọ̀kan bí àrùn, àìsàn, àti àwọn ìdánwò lóríṣiríṣi. Àmọ́ ogun àjàkúakátá ni èyí tíí kan ará-ilé kan ará oko. Kódà a máa dé bá ‘jẹ́jẹ́ mi ni mo jókòó’. Adéoyè (2005:295) ní “Kí irú ogun báyìí tó bẹ̀rẹ̀, orin níí kọ́kọ́ ṣaájú òwe, ọ̀tẹ̀ níí sì í ṣaájú ìjà’’. Oríṣiríṣi ohun ni ó le fa ogun jíjà láwùjọ ẹ̀dá káríayé. Yorùbá bọ̀, wọ́n ní ‘ẹ̀ṣẹ́ kan kì í ṣàdéédé ṣẹ́’. Lára àwọn nǹkan tí

àwọn Yorùbá àti àwọn onímọ̀ nípa ogun jíjà ní ó máa ń fa ogun jíjà láwùjọ ẹ̀dá ènìyàn, láìyọ ilẹ̀ Yorùbá sílẹ̀, ni ẹ̀mí ìlara àti ìrẹ́jẹ, ààlà ilẹ̀, sùnmọ̀mí gbígbé, gbígbẹ́sẹ̀ lé ohun-ìní ẹlòmíràn, fífẹ́ fi alágbára hàn láàrin àwọn ìlú tàbí ẹ̀yà méjì, àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ. Ìsọ̀rí kejì yìí sì ni ó kàn wá nínú iṣẹ́ yìí láti ṣe àgbéyẹ̀wò àwọn iṣẹ́ pàtàkì tí àwọn Yorùbá máa ń forin ṣe nígbà tí ogun àjàkúakátá yìí bá ṣẹlẹ̀ nílẹ̀ wọn.

## Tíọ́rì Soṣíọ́lọ́jì Lítíréṣọ̀

Tíọ́rì jẹ́ ohun-èlò tàbí irinṣẹ́ ti aṣèwádìí máa ń lò láti ṣe àgbéyẹ̀wò tàbí ìtúpalẹ̀ iṣẹ́-ọnà. Adéyẹmí (2006:8) ní 'Tíọ́rì dàbí abẹfẹ́lẹ́ ìmọ̀ tí a fi ń la ìfun àti ẹ̀dọ̀ iṣẹ́ kan'. Oríṣiríṣi ni àwọn tíọ́rì tí ó wà tí a lè lò láti ṣe ìtúpalẹ̀ iṣẹ́ ọnà lítíréṣọ̀. Kò sì sí àṣàdànù nínú gbogbo àwọn tíọ́rì ọ̀hún. Ṣùgbọ́n fún pàtàkì iṣẹ́ yìí, tíọ́rì ìmọ̀ ìbára-ẹni-gbé-pọ̀ ti lítíréṣọ̀ ni a yàn láàyò. Ìdí ni pé a gbà pé ó kúnjú ìwọ̀n láti sọ òkodoro ọ̀rọ̀ tó wà láàrin iṣẹ́-ọnà, oníṣẹ́ ọnà àti àwùjọ.

Ọ̀pọ̀lọpọ̀ àwọn onímọ̀ lítíréṣọ̀ ni wọ́n ti ṣiṣẹ́ lórí tíọ́rì yìí, tí wọ́n sì fìdí rẹ̀ múlẹ̀ pé èso àwùjọ ni lítíréṣọ̀ jẹ́. Ó sì hàn pé Hippolyte Taine tí í ṣe ọmọ ilẹ̀ Faransé ni ó ṣe agbátẹrù tíọ́rì yìí kí ó lè rọrùn fún àwọn lámèétọ́ láti mọ ìbáṣepọ̀ kò-lẹ́gbẹ́ tí ó wà láàrin iṣẹ́-ọnà (lítíréṣọ̀), oníṣẹ́ ọnà (akéwì tàbí òǹkọ̀wé) àti àwùjọ tó bí àwọn méjéèjì. Òye èyí hàn nínú iṣẹ́ àwọn onímọ̀ lítíréṣọ̀ bí Ọ̀pẹ́fèyítìmí (1997), Adéyẹmí (2005), Fátúrótì (2010) àti Ìlọ̀rí (2017). Ìlọ̀rí (2017:162) ní:

> Ó yẹ kí á fi òté lé e pé àwùjọ ló bí lítíréṣọ̀. Èso àwùjọ ni, orí ìṣẹ̀lẹ̀ tó bá ṣẹlẹ̀ láwùjọ ni lítíréṣọ̀

> ń dá lé. Inú àwùjọ ni gbogbo iṣẹ́ ọnà ti ṣẹ̀, tí wọ́n sì ń gbilẹ̀ si. Lítíréṣọ̀ yówù kó jẹ́ orí ìṣẹ̀lẹ̀ àwùjọ ló dá lé lórí, yálà àwùjọ ènìyàn, ẹranko tàbí àwọn ẹ̀dá abàmì.

Èrò yìí wà ní ìbámu pẹ̀lú orin tí ó jẹ́ àfojúsùn wa nínú iṣẹ́ yìí tí í ṣe iṣẹ́-ọnà lítíréṣọ̀ tí ó jẹ́ ẹ̀ka kan nínú ewì alohùn.

Àwùjọ ló bí orin ajẹmógun wọ̀nyí, èso àwùjọ Yorùbá ni pẹ̀lú; bẹ́ẹ̀ ni orí ìṣẹ̀lẹ̀ tó ṣẹ̀ láwùjọ Yorùbá nígbà tí wọn ń jagun tàbí bára wọn ṣọ̀tẹ̀ ni àwọn orin náà dá lé. Àwùjọ Yorùbá sì ni gbogbo ogun jíjà náà ti ṣẹlẹ̀. Èyí túmọ̀ sí pé a kò lè ya àwọn ẹ̀ta-òkò wọ̀nyí kúrò lára wọn, nítorí pé ìṣẹ̀lẹ̀ àwùjọ ló bí èrò ọkàn ọ̀kọrin ní irú àwùjọ yówù tí ọ̀kọrin bẹ́ẹ̀ bá bá ara rẹ̀. Inú àwùjọ ni ọ̀kọrin/akéwì ti wá, ó fi orin tí ó kọ pàrokò àwọn ìṣẹ̀lẹ̀ àwùjọ sí àwọn olùgbọ́ rẹ̀. Èyí fi hàn pé àwọn ènìyàn tó wà ní àwùjọ rẹ̀ ni ó kọ orin ọ̀hún fún láti mọ ohun tó ń ṣẹlẹ̀ lọ́wọ́lọ́wọ́, tàbí èyí tó ti ṣẹlẹ̀ tẹ́lẹ̀ àti láti jẹ́ kí àwọn ènìyàn mọ̀ nípa ohun tó ṣeé ṣe kí ó ṣẹlẹ̀ lọ́jọ́ iwájú. Ó sì tún fi èrò rẹ̀ hàn nípa àwọn àkíyèsí tí ó ṣe nípa àwọn ìṣẹ̀lẹ̀ náà.

Soṣíọ̀lọ́jì lítíréṣọ̀ fi hàn pé díńgí tí a fi ń wo àwùjọ ẹ̀dá ni lítíréṣọ̀ jẹ́. Laurenson àti Swingwood (1971) nínú Ìlọ̀rí (2017:163) fi hàn pé Lious De Bonald (1754 – 1840) ló sọ ojú abẹ níkòó pé díńgí àwùjọ ni lítíréṣọ̀ jẹ́ nínú ohun tí ó pè ní ''Mirror Image Approach''. David Bleich (1976:7) jẹ́ kí á mọ̀ pé:

> Literature is a reflection of people, and in it we can see human problems and concerns that we are going through ourselves.
>
> Lítíréṣọ̀ jẹ́ àwòjiìji ènìyàn, nínú rẹ̀ ni a ti lè rí ìṣòro àwa ẹ̀dá àti àwọn nǹkan tó kàn wá gbọ̀ngbọ̀n tí àwa tìkara wa ń là kọjá.

Àwọn agbátẹ̀rù tíọ́rì yìí gbàgbọ́ pé aṣèwádìí gbọ́dọ̀ rí i dájú pé kókó-ọ̀rọ̀ iṣẹ́-ọnà lítíréṣọ̀ bá ìṣẹ̀lẹ̀ tó ń ṣẹlẹ̀ lójoojúmọ́ mu. Bí a bá wo àwọn orin ajẹmógun tí a gbé yẹ̀wò níbí, a ó rí i pé wọ́n tọ́ka sí àwọn ìṣẹ̀lẹ̀ tí ó ṣẹ̀ láwùjọ Yorùbá ní àwọn àkókò kan tí wọ́n sì ń gbé àwọn kókó-ọ̀rọ̀ tó jẹ àwọn tó kọrin náà nígbà náà jáde kí tonílé-tàlejò lè mọ ohun tí ó jẹ wọ́n lógún, àti pé irú àkíyèsí tí wọ́n ṣe nípa àwọn ìṣẹ̀lẹ̀ àwùjọ náà.

Ohun tí ó jẹ wá lógún nínú iṣẹ́ yìí ni àlàyé tí Laurenson àti Swingwood (1971:107) ṣe pé ó rọrùn fún onímọ̀ lítíréṣọ̀ tí ó ṣe àmúlò tíọ́rì Soṣíọ́lọ́jì Lítíréṣọ̀ láti rí oníṣẹ́ ọnà (bí àpẹẹrẹ ọ̀kọrin/akéwì) gẹ́gẹ́ bí ẹni tó ń sọ bí àwùjọ ṣe rí ní àkókò kan nípasẹ̀ iṣẹ́-ọnà (orin ní pàtàkì) tó fi ń ta àwùjọ jí. Ní ìbámu pẹ̀lú àlàyé òkè yìí, a ó wo iṣẹ́ tí àwọn tó kọrin ajẹmógun ń fi orin wọ̀nyí jẹ́ láwùjọ Yorùbá. Irú iṣẹ́ tí wọ́n fi jẹ́ tàbí àrokò tí wọ́n fi pa pẹ̀lú ìdí tí wọ́n fi lò wọ́n nígbà náà yóò hànde nínú ìtúpalẹ̀ wa. Èyí yóò sì sọ ipa pàtàkì tí àwọn orin náà kó ní àwùjọ àwọn tó lò wọ́n nílẹ̀ Yorùbá nígbà náà.

Ọ̀kọ̀ọ̀kan àwọn orin tí a yàn fún àtúpalẹ̀ yìí ni yóò sọ kókó iṣẹ́ tí àwọn tó kọrin wọ̀nyí ń ṣe láwùjọ Yorùbá, àti

ìbáṣepọ̀ tó wà láàrin àwọn olùgbé àwùjọ náà nígbà náà àti àwọn ìṣẹ̀lẹ̀ tí ó ṣe okùnfà kíkọ àwọn orin ọ̀hún. Ìgbà àti àsìkò tí wọ́n kọ àwọn orin náà kò ní gbẹ́yìn nínú àlàyé wa gẹ́gẹ́ bí ó ṣe hàn nínú àgbékalẹ̀ àwọn orin náà.

## Ìgbà tí àwọn Orin Ajẹmógun máa ń wáyé nínú Ètò Ogun Jíjà nílẹ̀ Yorùbá

Bí ohun gbogbo ṣe wà ní ètò ní ètò ní àwùjọ Yorùbá, náà ni àwọn Yorùbá máa ń lo àwọn orin ajẹmógun nígbà tí ó yẹ. Wọn kì í nasẹ̀ kí wọn tó jókòó, bẹ́ẹ̀ ni wọn kì í kàn máa kọrin ajẹmógun nígbà tó bá wù wọ́n, bí kò ṣe nígbà tó bá yẹ. Yorùbá kì í gbọ́mọ Ọbà fún Ọ̀ṣun rárá. Ọ̀ná mẹ́ta ni a lè pín ìgbà tí àwọn orin ajẹmógun máa ń wáyé tàbí tí àwọn Yorùbá máa ń kọrin ajẹmógun nínú ètò ogun jíjà nílẹ̀ wọn sí. Àwọn ìgbà náà ni:

a. kí ogun jíjà tó bẹ̀rẹ̀ tàbí ní ìbẹ̀rẹ̀ ogun jíjà
b. nígbà tí ogun jíjà ń lọ lọ́wọ́
d. nígbà tí ogun jíjà bá parí

### *Orin ajẹmógun ṣáájú ogun jíjà tàbí ní ìbẹ̀rẹ̀ ogun jíjà*

Àwọn Yorùbá máa ń kọ àwọn orin ajẹmógun wọ̀nyí, yálà kí ogun jíjà tó bẹ̀rẹ̀ tàbí ní ìbẹ̀rẹ̀ ogun jíjà. Ní ọ̀pọ̀ ìgbà, àwọn orin wọ̀nyí ló máa ń dá rúgúdù sílẹ̀ tógun jíjà fi máa ń wáyé láàrin ìlú méjì tàbí jù bẹ́ẹ̀ lọ. Ó sì le jẹ́ èyí tí ìlú kan fi pe òmíràn níjà. Yorùbá lè lo orin wọ̀nyí ṣaájú ogun tàbí ní íbẹ̀rẹ̀ ogun jíjà láti mú orí àwọn ọmọ ogun yá àti láti kì wọ́n láyà.

Àpẹẹrẹ irúfẹ́ orin bẹ́ẹ̀ ni èyí tí àwọn ọmọ Yorùbá máa ń ko ní ìgbà ti wọ́n bá ń lọ sí ojú ogun. Ọkan nínú àwọn orin náà nìyí:

Ìpàdé dojú àlà
Ìpàdé dojú àlà
Bíkún ló loko ni,
Bí tàkúté ni.
Ìpàdé dojú àlà.

Àwọn ọmọ ogun lè kọ orin yìí pàdé àwọn ọ̀tá wọn. Orin náà ń fi hàn pé àwọn ọmọ tó ń kọ orin yìí níí lọ́kàn pé àwọn ń lọ fi àgbà hàn àwọn ọ̀tá wọn ní ojú ogun ni.
Òmírà ni èyí tí Ògúnmọ́lá ti ilẹ̀ Ìbàdàn ní kí àwọn onílù rẹ̀ àti àwọn onílù àwọn ìjòyè rẹ̀ kọ láti fi hàn pé òun ti ṣetán láti kó ogun ja àwọn Ìjàyè. Orin náà nìyí:

À fòkè,
À fi'gbó,
Kò sẹ́ni tí ó lè dúró. Johnson (1921: 423)

Orin yìí kó ìpayà àti jìnnìnjìnnìn bá àwọn Ìjàyè nígbà tí wọ́n gbọ́ ọ. Inú wọ́n sì bàjẹ́ pé Ìbàdàn tún gbé ogun káwọn mọ́lé.

Òmíràn ni orin tí àwọn Ìsẹ́yìn kọ láti fèrò ọkàn wọn hàn pé àwọn ò bẹ̀rù Ìbàdàn rárá, pé tí wọn ò bá tọwọ́ ọmọ wọn bọṣọ, àwọn á dojú ogun kọ Ìbàdàn. Ìsẹ́yìn kò ṣàdéédé kọrin náà, bí kò ṣe ìwà ìfọwọ́-ọlá gbáni lójú tí a gbọ́ pé àwọn ọmọ Ìbàdàn kan ń hù sí wọn. Orin tí wọ́n kọ náà nìyí:

Ìbàdàn tí ó kọ̀,
Tí kò lọ.
Awowo á wo ó. (ibid:421)

Ọ̀jẹ̀labí ni ọmọ Ìbàdàn tí wọ́n lé tí kò lọ. Dípò kó kúrò ní Ìsẹ́yìn, ní í ṣe ló tùn ń dáná sun ilé àwọn Ìsẹ́yìn. Èyí mú kí àwọn Ìsẹ́yìn fòkúta lé e jáde kúrò ní Ìsẹ́yìn láìkọ ohun tó le dà láàrin àwọn àti Ìbàdàn. Àmọ́, Ìbàdàn pẹ̀lú kò dákẹ́ rárá, àwọn náà forin dá Ìsẹ́yìn lóhùn pé:

A fàdàmọ̀ dá'mọ lẹ́kun Awowo.

### *Orin ajẹmógun nígbà tí ogun jíjà ń lọ lọ́wọ́*

Orin wọ̀nyí ni àwọn Yorùbá máa ń kọ lójú ogun, yálà láti fi ṣe ìkìlọ̀ fún àwọn ọmọ ogun tàbí ará ìlú, tàbí tí wọ́n máa ń lò láti mú àwọn ọmọ ogun lọ́kàn le, àti láti ṣe kóríyá fún àwọn jagunjagun kí wọ́n lè jàjàyè. Díẹ̀ lára àwọn orin náà ni wọ̀nyí:

Ìbíkúnlé,
A ó ṣe wọ́n,
A ó ṣe wọ́n,
Ẹgbá kò mọ ogun jíjà,
A ó ṣe wọ́n. Johnson (1921:414)

Ògúnmọ́lá ló kọrin yìí nígbà tó ṣàbẹ̀wò sí àwọn ọmọ ogun Ìbàdàn tí Balógun Ìbíkúnlé jẹ́ olórí fún ní àsìkò tí ogun Ìjàyè ń lọ lọ́wọ́ láàrin Ìbàdàn, Ìjàyè àti Ẹ̀gbá. Ó kọrin náà láti jẹ́ kí Balógun Ìbíkúnlé mọ̀ pé àwọn ọmọ ogun Ẹ̀gbá kò mọ̀ bí ó ti yẹ kí wọ́n jà ogun náà lájàyè. Òkè lálá ni àwọn jagunjagun Ẹ̀gbá ń yìnbọn sí, nítorí pé wọ́n kò fìgbà kan kọ́ bí a tí jagun bíi ti àwọn Ìbàdàn. Àjàyí àti Smith (1971:29) tilẹ̀ kín èyí lẹ́yìn nígbà tí wọn sọ pé "The Yoruba wars were fought with

only a limited regard for strategy" (Àwọn ogun tí àwọn jà di jíjà láì ní ètò kan gúnmọ́).

Johnson (1921:156) kín ọ̀rọ̀ àwọn onímọ̀ òkè yìí lẹ́yìn nígbà tí ó sọ pé:

> There never was or has been a standing army, nor any trained soldiers (except at Ibadan latterly where the idea began to germinate, and some of the chiefs had a number of their slaves trained solely for war; some chiefs had also a corps of boys, not to bear arms, but to be attendant on them in battle, in order to farmiliarise them with the horrors of war!.
>
> Kò sí àgbékalẹ̀ àwọn ọmọ ogun kankan rí, bẹ́ẹ̀ ni kò sí akọ́ṣẹ́mọṣẹ́ ọmọ ogun (yàtọ̀ sí èyí tó wà nígbẹ̀yìngbẹ́yín ní Ìbàdàn níbi tí èrò náà ti bẹ̀rẹ̀ sí í hù jáde, tí ọ̀pọ̀ àwọn ìjòyè sì ní ọ̀pọ̀ ẹrú tí wọ́n kọ́ ní ogun jíjà; ọ̀pọ̀ àwọn ìjòyè tún ní àgbáríjọ àwọn ọmọkùnrin, tí kì í ṣe láti gbé ohun ìjà, ṣùgbọ́n láti wà pẹ̀lú wọn lójú ogun, ní ọ̀nà à ti jẹ́ kí wọ́n mọ̀ nípa àwọn làlúrí ogun!.

Orin yìí sọ àléébù àwọn jagunjagun Ẹ̀gbá, èyí sì mú kí àwọn Ìbàdàn borí Ẹ̀gbá nígbà ogun náà. Abraham (1958:535) jẹ́ ká mọ̀ pé kì í ṣe Ẹ̀gbá nìkan ni àwọn Ìbàdàn ṣẹ́gun nínú ogun Ìjàyè náà, ó ní Ìjàyè pẹ̀lú forí ṣọta ogun náà lẹ́yìn tí Kúrunmí kú tán ní ọdún 1862. Ohun tí ó sọ nìyí:

> …from 1860 – 1862, Ìjàyè war raged, Ìbíkúnlé (the Balógun of Ìbàdọ̀n) destroying Ìjàyè. This

> war was won by Ìbàdọ̀n in 1862. Some months after the death of Kúrunmí.
>
> ...láti 1860 – 1862, Ogun Ìjàyè di jíjà, Ìbíkúnlé (Balógun Ìbàdàn) run Ìjàyè. Ìbàdàn ni ó sì borí nínú ogun náà ní 1862 lẹ́yìn oṣù díẹ̀ tí Kúrunmí ti kú.

Àwọn jagunjagun Ìbàdàn tún kọrin kan bú àwọn Ìjẹ̀bú nígbà tí wọ́n ṣígun pàdé nígbà ogun Ìpẹ́ru. Orin tí àwọn Ìbàdàn kọ náà nìyí:

> Ìjẹ̀bú kò pé okòó owó,
> Nítorí ẹrú lá ṣe ń lọ.

Àwọn jagunjagun Ìbàdàn fẹnu ṣáátá àwọn ọmọ ogun Ìjẹ̀bú nígbà ogun Ìpẹ́ru. Ìdí tí Ìbàdàn fi fẹnu tẹ́ńbẹ́lú Ìjẹ̀bú ni pé kò sí ogun tó pa àwọn méjéèjì pọ̀ tí àwọn Ìbàdàn kò ti ṣẹ́gun àwọn Ìjẹ̀bú.

Àwọn Ògbómọ̀ṣọ́ kọrin kan nígbà ogun Àgbẹ̀kọ̀yà tí ó wáyé ní ọdún 1968 sí 1970 ní Ògbómọ̀ṣọ́ àti agbègbè Ọ̀yọ́. Orin náà lọ báyìí:

> Orí múbà ni ó kún un
> Orí múbà ni ó kún un
> Kòtò kan gìrìwò
> Tí ń bẹ lÓwódé
> Orí múbà ni ó kún un

Àwọn ará ìlú Ògbómọ̀ṣọ́ forin òkè yìí bú Baálẹ̀ Ọlájídé Ọláyọdé (Ṣọ̀ún Ògbómọ̀ṣọ́ ìgbà náà) tí ó kó àwọn ọlọ́pàá orí-ìrìn (ọlọ́pàá kògbérèégbè) wá sí Ògbómọ̀ṣọ́ láti Ìbàdàn kí

wọ́n lè dá àwọn tó ń fẹ̀hónú hàn nípa ìwà ìmọtara-ẹni tí Baálẹ̀ náà lórí ṣíṣe àlékún iye owó-orí tárá ìlú ń ṣan tẹ́lẹ̀ láìbìkítà ohun tó lè tibẹ̀ yọ. Lóòótọ́ ni pé ọ̀pọ̀ ẹ̀mí ará ìlú ló lọ nínú ogun ọ̀hún, àmọ́ kì í ṣe àwọn nìkan, Baálẹ̀ àti ọ̀pọ̀ àwọn ọlọ́pàá àti ọmọ ogun tó kó wá láti Ìbàdàn ló ṣègbé sínú ogun náà. Bí a bá ń ṣe é, ilé ayé ló ń gbé, a kì í ṣe é ń bẹ lóde ọ̀run lórọ̀ náà wá dà.

### *Orin ajẹmógun nígbà tí Ogun jíjà bá parí*

Oríṣríṣi orin ajẹmógun ni àwọn ọmọ ogun àti àwọn ará ìlú máa ń kọ ní kété tí ogun jíjà bá ti parí. Àwọn orin wọ̀nyi sábàá máa ń kéde pé ogun kan wá sópin tàbí kí wọ́n kéde ìṣẹ́gun tí ó fara hàn nínú ogun náà Wọ́n sì máa ń fi orin wọ̀nyí gbóríyìn fún àwọn jagunjagun láwùjọ Yorùbá ní gẹ́rẹ́ tí ogun parí. Ọ̀kan lára àwọn orin bẹ́ẹ̀ ni èyí tí àwọn Ìjẹ̀bú kọ láti fìdùnnú wọn hàn nígbà tí àwọn Ẹ̀gbá kéde fún àwọn Ìjẹ̀bú pé àwọn kò jagun mọ́ ní àsìkò ogun Òwìwí. Àwọn Ìjẹ̀bú kọ orin náà láti fi bínú wọn ṣe dùn tó hàn. Ìdí ni pé wọn kó fẹ́ kógun náà ṣípá mọ́ àwọn lọ́wọ́, bẹ́ẹ̀ ni inú wọ́n dùn pé àlàáfíà á jọba lẹ́yìn ogun. Orin náà nìyí:

Ọmọdé Ìjẹ̀bú,
Ẹ kú ewu.
Àgbà Ìjẹ̀bú,
Ẹ kú ewu.
Ọ̀tẹ̀ yìí jàjà parí o. Johnson (1921:301)

Òmíràn ni orin tí akéwì Kúrunmí ti Ìjàyè kọ fi yin Kúrunmí ní kété tógun Gbánámú parí. Orin ọ̀hún nìyí:

Ó pa Máyẹ̀,
Ó pa Ọ̀gíní,
Ó pa Dégẹṣin,
Ó fi ọ̀kọ̀ ti Ifẹ̀ láyà. (ibid: 286)

Àwọn akéwì Kúrunmí ti ilẹ̀ Ìjàyè kọ orin òkè yìí láti gbóríyìn fún ọ̀gá wọn nígbà tí ó ṣẹ́gun àwọn ọ̀tá rẹ̀. Lára àwọn olórí ogun tí Kúrunmí pa nígbà ogun Gbánámú náà ni Máyẹ̀ (Baálẹ̀ Ìbàdàn àkọ́kọ́, tí a gbọ́ pé láti Ifẹ̀ ló ti wá), Ọ̀gíní àti Dégẹṣin sì jẹ́ olórí ọmọ ogun Ẹ̀gbá nígbà náà.

## Iṣẹ́ Pàtàkì tí Orin ń ṣe Nínú Ètò Ogun Jíjà

Iṣẹ́ pàtàkì ni àwọn Yorùbá máa ń fi àwọn orin ajẹmógun ṣe nínú ètò ogun jíjà ní àwùjọ wọn. Yorùbá máa ń kọrin yìí láti ṣe kóríyá fún àwọn jagunjagun, láti kì wọ́n láyà àti láti mú wọn lọ́kàn le tí wọ́n bá ń lọ ojú ogun (Adú àti Adéríbigbé, 2016:405). Àwọn iṣẹ́ pàtàkì tí àwọn orin ajẹmógun wọ̀nyí ń ṣe kò tán síbẹ̀, a tún rí ọ̀pọ̀lọpọ̀ ipa pàtàkì tí orin ogun máa ń kó nínú ètò ogun jíjà láwùjọ Yorùbá. Orin ogun lè ṣiṣẹ́ ìfẹ̀hónúhàn, ìṣọ̀tẹ̀, ìpẹ̀tùsááwọ̀, ìkìlọ̀, ìkéde ogun ṣíṣẹ́, àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ. Awẹ́ (1975:268) fi ipò pàtàkì tí ewì alohùn wà nínú ètò ogun jíjà láwùjọ hàn nígbà tó ń sọ̀rọ̀ nípa oríkì:

> In any exercise aimed at examining the nature of warfare among the Yorùbá, one particular source cannot be overlooked. This is the oríkì, praise poem or citation on an object.

> Ní ìgbàkúùgbà tí a bá gbìyànjú láti ṣe àgbéyẹ̀wò ogun jíjà láàrin àwọn Yorùbá, orísun kan pàtàkì ni a kò lè fojú parẹ́. Òun náà ni oríkì, ewì ìgbóríyìn tàbí ìpàátó lórí nǹkan kan.

Àmọ́ kì í ṣe oríkì nìkan ni èyí báwí, lára àwọn tí ó kù ni orin tí a ń gbé yẹ̀wò níbí. Adégbójù (2016:429) jẹ́ kí á mọ iṣẹ́ pàtàkì tí àwọn orin ogun ń ṣe nínú ètò ogun jíjà nílẹ̀ Yorùbá nígbà tó sọ báyìí:

> Lásìkò ogun ni irú orin báyìí máa ń wáyé láti lè mú kí àwọn ọmọ ogun ó jí gìrì kí orí wọn ó le wúlé láti ja àjàṣẹ́gun lójú ìjà. Wọn á sì tún máa lò ó láti fi ṣe àjọyọ̀ lẹ́yìn ìṣẹ́gun.

Àpẹẹrẹ iṣẹ́ pàtàkì tí àwọn orin ajẹmógun máa ń ṣe nínú ètò ogun jíjà ni wọ̀nyí, gẹ́gẹ́ bí ó ṣe hàn nínú ètò ogun jíjà nílẹ̀ Yorùbá.

### *Ìforin ogun ṣìpẹ̀*

Ìran Yorùbá máa ń forin ṣìpẹ̀ ní àsìkò ogun jíjà. Wọ́n lè kọrin kí wọ́n má baà mú wọn mọ́ àwọn tí yó pẹ̀lú àwọn jagunjagun lọ sógun. Ìdí ni pé wọ́n lè má padà darí wálé mọ́. Ṣebí ìbẹ̀rẹ̀ ogun ni ènìyàn ń mọ̀, kò ṣẹ́ni tíí mọ òpin rẹ̀. Àwọn Ẹ̀gbá máa ń kọrin kan nígbà tí wọ́n ń jagun Àdùbí. Ohun tí ó bí orin náà ni pé bí Ogun Àdùbí ṣe ń jà lọ́wọ́ ni àwọn aláṣẹ ìlú Abẹ́òkúta bí Aláké Gbádébọ̀, àti Adégbóyèga Ẹdun, tí ó jẹ́ Akọ̀wé ìlú nígbà náà, ń kó ẹnikẹ́ni tí wọ́n bá fura sí pé ó wà

nídìí ọ̀tẹ̀ tó bí Ogun Àdùbí lọ sójú ogun láìṣẹ̀, láìrò. Orin náà lọ báyìí:

> Ẹ má mà rán mi rÀdùbí.
> Ẹni ẹ rán lọ,
> Kò ì bọ̀ o.
> Ẹni ẹ rán lọ,
> Kò ì dé. Ajíkòbi (2013:26)

Ogun Àdùbí yìí ni wọ́n ní ó wáyé láàrin ọdún 1914-1918. Ó hàn pé àsìkò kan náà ni Ogun Àdùbí àti Ogun Àgbáyé àkọ́kọ́ wáyé.

Àwọn Ìlaàró kọ orin kan ṣìpẹ̀ sí àwọn afọbajẹ ti ilẹ̀ Ìlaàró nígbà tí àwọn ọmọyè mú ọ̀rọ̀ ọba jíjẹ ní 'bí o bá a, o pa á; bí o ò bá a, o jù ú ní kùmọ̀'. Àwọn ará ìlú kọ orin ṣìpẹ̀ pé kí àwọn afọbajẹ gbé adé lé ẹni tó yẹ lórí. Nínú orin wọn ọ̀hún, ó hàn pé Ọmọọba Adékúnlé ni oyè náà tọ́ sí nìgbà náà. Orin tí wọ́n kọ fi ṣìpẹ̀ náà nìyí:

> Bó bá jẹ́ bẹ́ẹ̀ níí bá máa dà,
> Ká móyè f'Ádékúnlé o.
> Èdùdù Ọba Ìbèsè
> Ikú ẹ̀ ló pa Ọ̀tẹ̀ǹkan
> Ìyẹn ò tó mú ṣọgbọ́n dan
> Ẹ ń yankọ̀ firifiri.

Wọ́n fi orin òkè yìí ṣìpẹ̀ kí ogun 'ta ni oyè tọ́ sí' lè ròkun ìgbàgbé, kí àláàfíà lè jọba ní ìlú.

Ìjòyè kan láti Ifẹ̀ tí ó forí pèkùn sí Ìbàdàn, tí ó sì tún jẹ́ olórí jagunjagun kọrin kígbe ṣìpẹ̀ sí àwọn tí wọ́n mú un ní ìgbèkùn nígbà Ogun Gbánámú pé kí àwọn ìjòyè Ìbàdàn àti

àwọn olórí ogun yòókù má ṣe dá ìgbẹ́jọ́ rẹ̀ ṣe, kí wọ́n fi ojú rẹ̀ kan Lákanlẹ̀ tí ó jẹ́ Aláṣẹ àwọn Ọ̀yọ́ tí ó wọ̀ sí Ìbàdàn lẹ́yìn tí Oorun àti Gbágùrá fọ́. Wọ́n mú un nígbèkùn nítorí pé ó pa ará Ọ̀yọ́ kan lọ́nà àìtọ́, ó sì ṣá kúrò ní ìlú. Orin tí ó kọ ṣìpẹ̀ náà nìyí:

Ẹ má dá a ṣe,
Ẹ fi ojú mi kan alàgbà!
Ẹ má dá a ṣe,
Ẹ fi ojú mi kan Lákanlẹ̀. Johnson (1921: 286)

Yorùbá bọ̀, wọ́n ní 'kò sẹ́ni tí Ọlọ́run kò lè mú'. Máyẹ̀ rò pé òun lè múwà ìbàjẹ́ rẹ̀ jẹ, àmọ́ ọ̀rọ̀ gbojú kejì yọ sí i. Ọmọ ogun lásán, tí kì í ṣe olórí ogun ló mú Máyẹ̀ nígbèkùn tí ó sì bẹ́ ẹ lórí.

## *Ìforin ogun kéde ogun jíjà*

Nílẹ̀ Yorùbá, orin ni ohun pàtàkì àkọ́kọ́ tí wọ́n fi máa ń mọ̀ pé àwọn ìlú kan fẹ́ dìde ogun sí ara wọn. Ó máa ń hàn nínú orin wọn pé wọ́n fẹ́ lọ dojú ogun kọ àwọn ènìyàn kan tàbí ìlú kan. Irú àwọn orin wọ̀nyí ni a lè sọ pé wọ́n fi ń kéde ogun jíjà. Nínú ọ̀tẹ̀ tó wáyé láàrin àwọn Elékòó mẹ́ta (Elékòó Èṣùgbàyí Dòsùmú, Elékòó Ìbíkúnlé Akítóyè, àti Elékòó Sànúsí Olúsì) bí ó ṣe hàn ní Ajíkòbi (2013:40-41), àwọn ọmọ Kòsọ́kọ́ kọrin ṣí gàngàn lọ sí Ìgà Ìdúǹganràn nígbà tí wọ́n gbọ́ pé Ọba Olúwọlé dá sẹ̀ríà fún ẹrú Kòsọ́kọ́ kan ní Ìgà. Orin tí wọ́n kọ náà nìyí:

B'ó lè d'ogun kó d'ogun.
B'ó lè d'ọ̀tẹ̀ kó dọ̀tẹ̀.

Òjò p'ewée kókò,
Bó lè ya, kó ya.

Ọba Olúwọlé ló padà borí ọ̀tẹ̀ náà, Kòsọ́kọ́ sì ṣá kúrò ní Èkó lọ sí Àpá nígbà náà.

### *Ìforin ọ̀tẹ̀ ṣáátá ọ̀tá ẹni*

Yorùbá máa ń forin ọ̀tẹ̀ bu ẹnu àtẹ́ lu ọ̀tá wọn nígbà ogun jíjà. Èyí sì máa ń wáyé nígbà tí ohun tí ọ̀tá bá rò sí ẹni tí wọ́n ń dìtẹ̀ mọ́ bá já sí pàbo. Àpẹẹrẹ irúfẹ́ orin bẹ́ẹ̀ ni èyí tí àwọn olùfẹ́ Baálẹ̀ Ọtunla tí ó jẹ́ ọmọ Baálẹ̀ Òjó Aburúmákùú ti Ògbómọ̀ṣọ́ gba ọ̀nà ẹ̀bùrú gorí oyè láìfi ti àwọn ìjòyè ìlú ṣe lẹ́yìn ikú baba rẹ̀. Àwọn ọ̀rẹ́ àti olùfẹ́ Baálẹ̀ Ọtunla kọ orin náà nígbà tí wọ́n gbọ́ pé àwọn ìjòyè ìlú fẹ́ rọ Baálẹ̀ Ọtunla lóyè láti fi bu ẹnu àtẹ́ lu ìwà tí àwọn ìjòyè fẹ́ hù nígbà náà. Ní òtítọ́, kì í ṣe Baálẹ̀ Ọ̀tunla ni ó kàn láti gun orí àpèrè ní ìgbà náà bí kò ṣe Baálẹ̀ Gbágun Ajagungbadé I. Orin tí wọ́n kọ ní ìgbà náà láti fi ẹnu ṣáátá àwọn ìjòyè ìlú nìyí:

Irọ́ ni wọ́n ń pa,
Èké ni wọ́n ń ṣe.
Ó dijọ́ ẹ bá fàtè mẹ́ja lódò,
Kí ẹ tó rọ́ba mú.

Aáwọ̀ yìí wáyé ní àárín ọdún 1869 àti 1870. Ìgbá tí ìlú ò fara rọ fún Baálẹ̀ Ọ̀tunla àti àwọn ẹmẹ̀wà rẹ̀ mọ́ ni Baálẹ̀ Ọtunla sá kúrò lórí oyè tí ó sì fi ìlú Ògbómọ̀ṣọ́ sílẹ̀. Kì í ṣe ojú bọ̀ọ̀rọ̀ ni wọ́n fi gba ọmọ ní ọwọ́ èkùrọ́ Baálẹ̀ Ọ̀tunla, àwọn jagunjagun Ògbómọ̀ṣọ́ tí ó ń ran àwọn Ìbàdàn lọ́wọ́ nínú

ogun Iléṣà ní láti padà wá sí ilé láti yanjú ọ̀ràn náà. Èyí sì mú kí aáwọ̀ bẹ́ sílẹ̀ tí Baálẹ̀ Ọ̀tunla sí fìlú sílẹ̀. Ni àwọn ìjòyè bá gbé Baálẹ̀ Gbágun gorí oyè.

Àwọn Yorùbá tún máa kọ orin bu ẹnu àtẹ́ lu èrò àwọn wọn ní ìgbà ti ọ̀tá bá rò pé ogun kan máa gbé wọn lọ tí ó sì jẹ pé wọ́n padà ṣẹ́ ogun náà tí ọ̀rọ̀ wá di pé 'Ẹni a rò pé kò le pàgọ́, wá di ẹni tó ń kọ́ ilé aláruru' ní ìgbẹ̀yìn. Irú orin bẹ́ẹ̀ ni ré è:

Kó wó,
Kó wó
Àràbà ò wó mọ́,
Ojú tìrókò!

Orin náà fi hàn pé ohun tí ọ̀tá gbèrò kò ṣẹ ní orí ẹni tàbí àwọn tí ó kọ orin náà.

**Ìforin ogun ṣe Iṣẹ́ Kóríyá fún àwọn Jagunjagun**

Ní ọ̀pọ̀ ìgbà ní àwọn Yorùbá máa ń kọrin ogun mú orí àwọn jagunjagun yá sí ogun jíjà kí wọ́n lè ṣẹ́gun ọ̀tá. Wọ́n sì máa ń fi irú orin bẹ́ẹ̀ ṣe iṣẹ́ ìmúlọ́kàn le fún àwọn ọmọ ogun wọn.
Àpẹẹrẹ irú orin bẹ́ẹ̀ ni èyí tí Ògúnmọ́lá ti Ìbàdàn kọ nígbà tí ó gẹṣin lọ ṣàbẹ̀wò sí àwọn ọmọ ogun Ìbàdàn nígbà ogun Ìjàyè pé:

Ìbíkúnlé,
A ó ṣe wọ́n,
A ó ṣe wọ́n,
Ẹ̀gbá kò mọ ogun jíjà,
A ó ṣe wọ́n.

Johnson (1921:414)

Orin yìí ṣe kóríyá fún àwọn jagunjagun Ìbàdàn, nítorí pé Ògúnmọ́lá ti forin sọ àléébù àwọn ọmọ ogun Ẹ̀gbá.

Orin mìíràn tí àwọn Yorùbá máa ń kọ́ kí ara àwọn ọmọ ogun lè yá fún ogun jíjà ni èyí tí wọ́n ní Kúnrunmí tí ó jẹ́ Ààrẹ-Ọ̀nà Kakaǹfò ilẹ̀ Yorùbá nígbà kan rí máa ń kọ ní ìgbá tí Olórí ọmọ ogun náà bá ń lọ sí ogun. Àwọn onílù àti ará ìlú ni wọ́n ní ó máa ń kọ orin ọ̀hún láfi fi mú Ààrẹ Kúnrunmí pé ó ti di òòrùn tí ó ń gbónná janinjanin tí ọ̀tá kan kò lè ṣíjú wò, tí ó sì ń jó àwọn ọ̀tá rẹ̀ lára. Orin ọ̀hún nìyí:

Kúnrunmí doòrùn,
Ó gbónná janinjanin.
Ààrẹ doòrùn,
Ó gbónná janinjanin.

Irú wọ̀nyí máa ń mú orí àwọn yá láti lọ sí ojú ogun ni, èyí yóò sì mú kí wọ́n lè fi gbogbo agbára wọn ja ogun náà. Ìdí ni pé bí wọ́n bá ṣẹ́gun, oríyìn á tún pọ̀ sí I ni.

### *Ìforin ogun fẹ̀hónú hàn*

Àwọn Yorùbá máa ń kọrin láti fẹ̀hónú hàn lòdì sí ohun tí àwọn ọ̀wọ́ ènìyàn kan bá ń ṣe ní àwùjọ wọn tí kò dára. Èyí sì máa ń wáyé nígbà tí aáwọ̀ bá wà, yálà láàrin àwọn ọ̀wọ́ méjì ní ìlú kan tàbí láàrin ìlú méjì tí wọn ń bá ara wọn jà. Àpẹẹrẹ èyí ni orin tí àwọn Ìsẹ́yìn kọ láti fi kọ ìwọ̀sí tí ìjọba ilẹ̀ Gẹ̀ẹ́sì fi lọ̀ wọ́n nípa owó-orí sísan fún Ọba Gẹ̀ẹ́sì èyí ó rán Captain Ross láti máa ṣe ní agbègbè Ẹkùn Ọ̀yọ́ àti ìlú Ọ̀yọ́ ní ọdún 1916. Nínú orin náà Ìsẹ́yìn kọ̀ jálẹ̀ pé àwọn ò san ìṣákọ́lẹ̀

kankan fún Ajẹ́lẹ̀ Captain Ross, wọ́n ní Asẹ́yìn ni ìṣákọ́lẹ̀ àwọn tọ́ sí. Orin tí wọ́n kọ ní ìgbà náà nìyí:

Ará Ọ̀yọ́ mỌba,
Ìsẹ́yìn ni ò mỌba.
Ará Ọ̀yọ́ mỌba,
Ìsẹ́yìn ni ò mỌba.
Èèyàn dúdú tó pe Rọ́ọ̀sì lẹ́jọ́.
Ará Ọ̀yọ́ mỌba,
Ìsẹ́yìn ni ò mỌba.

Orin yìí fi yé wa pé àwọn Ọ̀yọ́ mọ Ọba ilẹ̀ Gẹ̀ẹ́sì nítorí pé wọ́n ń san ìṣákọ́lẹ̀ fún Ajẹ́lẹ̀ Ross tí ó wà ní ẹ̀kún náà bí aṣojú Ọba Gẹ̀ẹ́sì, àmọ́, Ìsẹ́yìn kò mọ̀ ọ́n nítorí wọ́n kọ̀ láti san ìṣákọ́lẹ̀ fún Ajẹ́lẹ̀, tí wọ́n sì ń kó ìṣákọ́lẹ̀ tọ Asẹ́yìn lọ. Èyí di ogun di ọ̀ràn débi pé Ìjọba Gẹ̀ẹ́sì fi pańpẹ́ òfin mú àwọn Olórí ogun àti àwọn akọni Ìsẹ́yìn tí ó kọ ìyànjẹ náà.

## Ìforin Ogun ṣe Ìkìlọ̀

Àwọn àyàn máa ń fìlù kọrin kìlọ̀ fún ẹnikẹ́ni tó bá ń dáṣà kógun ṣẹlẹ̀ láwùjọ Yorùbá. Irú orin bẹ́ẹ̀ ni:

Bó bá burú tán,
Tìẹ nìkan ni yó dà.
Bó bá burú tán,
Ìwọ nìkan ni yó kù.

Àmọ́, ọ̀pọ̀ alétí lápá ẹ̀dá ni kì í gbọ́ irú ìkìlọ̀ àti ìmọ̀ràn àwọn onílù yìí, à fìgbà tógun ọ̀hún bá mú wọn roko-ẹ̀tẹ̀ àrèmabọ̀.

Àpẹẹrẹ orin ogun ajẹmọ́kìlọ̀ ni èyí tí wọ́n kọ kìlọ̀ fún Balógun Pópóọlá tilẹ̀ Ògbómọ̀ṣọ́ tí ó hàn nínú Oyèrìndé (1934) èyí tí Ọlátúnjí (1984:83) ṣe àmúlò:

Bí wọ́n ń lérí ogun,
Má ṣe bá wọn lérí ogun mọ́;
Bí wọ́n ń sọ̀rọ̀ ìjà,
Má ṣe bá wọn sọ̀rọ̀ ìjà mọ́.
A kì í sọ̀rọ̀ ìjà lójú ẹni tí kò le è nani.

Wọ́n gba Balógun Pópóọlá ní ìmọ̀ràn pé kó má ṣe dara pọ̀ mọ́ àwọn ọ̀tá ìlú tó ń gbìmọ̀ kógun ṣẹlẹ̀ nílùú. Orin yìí jẹ́ ká mọ̀ pé àwọn ará ìlú fẹ́ kí Balógun Pópóọlá yẹra fún àwọn ọlọ̀tẹ̀ tó fẹ́ gbómi ogun lénà. Ó sì hàn ní ìlà tó gbẹ̀yìn pé àwọn ọlọ̀tẹ̀ náà ò ní agbára láti ṣẹ́gun bí ogun bá tilẹ̀ ṣẹlẹ̀.

## Àgbálọgbábọ̀

A ti yẹ ipa pàtàkì tí orin ń kó nínú ètò ogun jíjà láwùjọ Yorùbá wò nínú àpilẹ̀kọ yìí. Ó sì hàn pé àwọn Yorùbá kò kóyán orin kéré láwùjọ wọn. Orin sì nìyí, okùn ẹ̀mí ogun jíjà ló jẹ́ nílẹ̀ Yorùbá. Ipò kòlẹ́gbẹ́ tí orin dì mú nínú ètò ogun jíjà láwùjọ Yorùbá níláti yé tẹrú-tọmọ, kí àwùjọ lè gòkè àgbà, kí àlàáfíà àti ìrẹ́pọ̀ sì lè jọba nílẹ̀ Yorùbá àti lórílẹ̀-èdè Nàìjíríà lápapọ̀. Kò yẹ kí á gbàgbé àwọn ìṣẹ̀lẹ̀ tó bí àwọn ogun tó wáyé nílẹ̀ Yorùbá, kí á má baà tún padà sí ẹsẹ àárọ̀.

Ìwádìí gbọ́dọ̀ jinlẹ̀ nípa àwọn ìṣẹ̀lẹ̀ àná, kí á lè ṣe àtúnṣe sí àwọn kùdìẹ̀-kudiẹ tó ṣẹlẹ̀ ní àná tó ń ṣe àkóbá fún ọjọ́ òní àwùjọ Yorùbá, tó sì le ní ìpalára fún ọjọ́ ọ̀la àwùjọ Yorùbá nípa wíwo ipa tí àwọn orin tí wọ́n lò kó nínú àwọn

ìṣẹ̀lẹ̀ náà. Yorùbá ní bọ́mọdé bá ṣubú, a wo iwájú; ìran àgbà tó ṣubú níí wẹ̀yìn wò kírú ìṣubú bẹ́ẹ̀ má baà lè wáyé mọ́.

Ìfeegun Òtòlò to àwọn ọ̀rọ̀ àti ìṣẹ̀lẹ̀ tó lè daáwọ̀, dogun dọ̀tẹ̀ ní ìtùnbí-ǹ-nùbí ni ó lè mú àwùjọ tòrò. Ẹlẹ́yàmẹyà kò dára rárá, ó ń sọ àwùjọ di isà òkú ni.

## Ìwé Ìtọ́kasí


Adébàjò, O. (2016). 'Àwọn Orin Fíìmù *Ṣaworo-Idẹ* àti *Agogo Èèwọ̀* Gẹ́gẹ́ bí Awòjìji Ìṣẹ̀lẹ̀ Ilẹ̀ Wa' nínú Adéléké, D. (Olóòtú) *Àṣà, Èrò àti Èdè Nínú Iṣẹ́-Ọnà Aláwòmọ́-Lítíréṣọ̀ Akínwùmí Ìṣọ̀lá*. Ìbàdàn: DB Martoy Books, pp. 245-259.

Adégbódù, O. (2016). 'Ìlò Orin nínú àwọn ìwé Àtinúdá Akínwùmí Ìṣọ̀lá' nínú Adéléké, D. (Olóòtú) *Àṣà, Èrò àti Èdè Nínú Iṣẹ́-Ọnà Aláwòmọ́-Lítíréṣọ̀ Akínwùmí Ìṣọ̀lá*. Ìbàdàn: DB Martoy Books, pp. 423-431.

Adéoyè, C. (2005). *Àṣà àti Ìṣe Yorùbá*. Ìbàdàn: University Press PLC.

Adéyẹmí, O. (2006). *Tíọ́rì Lítíréṣọ̀ ní Èdè Yorùbá*. Ìjẹ̀bú-Òde: Sebíotimọ Publications.

Akínyẹmí, A. àti Ajíbádé, O. (2016). 'Ìlò Lítíréṣọ̀ Alohùn Nínú *Ogún Ọmọdé* nínú Adéléké, D. (Olóòtú) *Àṣà, Èrò àti Èdè Nínú Iṣẹ́-Ọnà Aláwòmọ́-Lítíréṣọ̀ Akínwùmí Ìṣọ̀lá*. Ìbàdàn: DB Martoy Books, pp. 295-306.

Adú, O. àti Adéríbigbé, M. (2016). 'Ìlò Orin nínú Àwọn Fíìmù Àgbéléwò Akínwùmí Ìṣọ̀lá nínú Adéléké, D. (Olóòtú) *Àṣà, Èrò àti Èdè Nínú Iṣẹ́-Ọnà Aláwòmọ́-Lítíréṣọ̀*

*Akínwùmí Ìṣọ̀lá*. Ìbàdàn: DB Martoy Books, pp. 402-410.

Àjàyí, A. and Smith, R. (1971). *Yoruba warfare in the nineteenth century*. Ibadan: Ibadan University Press.

Ajíkòbi, O. (2013). *Ipa tí Orín kó Nínú Ọ̀tẹ̀ Elékòó Mẹ́ta*. Lagos: The Graphics Men.

________ (2000). *Oyínkán Ṣe Bẹbẹ.* Lagos: Prompt Books.

Bámidélé, L. (2000). *Literature and Sociology*. Ibadan: Stirling Horden Publishers Nigeria Limited.

Bleich, D. (1978). *Subjective Criticism*. Baltimore and London: Johns Hopkins University Press.

Fájẹ́nyọ̀, S. (2016). 'Àgbéyẹ̀wò Ìlò Ewì Alohùn Yorùbá Nínú Ẹfúnṣetán Aníwúrà tí Akínwùmí Ìṣọ̀lá Kọ' nínú Adéléké, D. (Olóòtú) *Àṣà, Èrò àti Èdè Nínú Iṣẹ́-Ọnà Aláwòmọ́-Lítíréṣọ̀ Akínwùmí Ìṣọ̀lá*. Ìbàdàn: DB Martoy Books, pp. 153-161.

Finnegan, R. (2012). *Oral literature in Africa.* United Kingdom: Open Book Publishers CIC Ltd.

Gbàdàmọ̀ṣí, O. (1980). *Literary study of political songs in Yorùbá.* B. A. Long Essay, Department of African Languages and Literatures, University of Lagos, Lagos.

Ìlọ̀rí, E. (2017). 'Lítíréṣọ̀ àti Ọ̀nà Ìbánisọ̀rọ̀ Ìgbàlódé: Àfihàn rẹ̀ nínú Ìtàn Àròsọ *Ká Rìn Ká Pọ̀* nínú Adéníyì Àkàngbé (Olóòtú)*YORÙBÁ: Journal of Yorùbá Studies Association of Nigeria*, Vol.8, no. 4, pp.160-177.

Ìṣọ̀lá, A. (2008). *Ṣaworoidẹ.* Ìbàdàn: University Press Plc.

Johnson, S. (1921). *The History of the Yorubas.* Lagos: CSS Bookshops Limited.

Lawrenson, D. àti Swingwood, A. (1971). *The Sociology of Literature*. London: Mac Gobbon and Kee.

Ọlátúnjí, Ọ. (1984). *Features of Yorùbá Oral Poetry*. Ìbàdàn: University Press PLC.

Ọ̀ṣọ̀bà, B. (2012). 'Songs in Yorùbá Drama: Illustration from Selected Yorùbá Home Videos' nínú *Ihafa: Journal of African Studies, Vol. 5 No 4*, pp.157-173.

Ọ̀wọ́adé, S. (2013). *Pàtàkì Ogunòjàlú sí Ìlú Ògbómọ̀ṣọ́*. Ìwé Àṣekágbá fún Oyè Bí-EÈ, Department of Linguistics, African and Asian Studies, University of Lagos, Lagos.

__________ (2017). *Oral Yorùbá Poetry in Ògbómọ̀ṣọ́ Traditional Political System*. M. A. Thesis, Department of Linguistics, African and Asian Studies, University of Lagos, Lagos.

Sotunsa, M. (2009). *Yorùbá Drum Poetry*. London: Stillwatersstudios.